# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. IV. No. 167. SATURDAY, SEPTEMBER 26, 1925. 4d.

***The People's Leading Vernacular Paper.***


SEP. 1925


## White's Golden Female Tonic
### (NATIVE)

A splendid Remedy for female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cramps, Ovarian Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A tendency to Miscarriage etc., etc.

**Price 10s. per Bottle.**

**Made and sold only by** VICTOR WHITE, Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*Packing & Postage 2/6d. extra.*

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.
OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilękę, Ile Ilękę, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilękę, orişirisi Ilękę wọnyi wa ni tita :—

Ilękę Oyinbo, Ilękę Rubber, Ilękę Olomi Wajì, Ilękę Onikękę, Ilękę Elejo, Ilękę Ayinrin, Ilękę Oniwõrò ati Fadaka, Ilękę Kerewu, Ilękę Jòjò, Ilękę Òlokuta, Ilękę Oloruka, Ilękę Ęlęranko, Ilękę Didan Yinrinyinrin, Ilękę Meremere, Ilękę Mọjọkun, Ilękę Adumãdan.

Ę wa wo Ile ọja wa ; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, jigi, Aşọ Aran, Ęrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Is'ọşọ, Ęrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni :— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# RE-OPENING

OF

# LEVER STORE

## BROAD STREET,

## LAGOS.

# 1ST OCTOBER

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

ONINI BABA EWU.

Ọgbẹni D. L. Oshodi ti 36, Idoluwo *Street, Lagos* ni orişirişi *Ivory Coat & Trouser Button* ( Onini ) fun tita kosi aşọ ti ko ni *button* to yẹ. O si ni wabi-wọsi ero-ija *Tailor* (*Tailors Trimmings*) ni tita bakanna; o si nfa'şọ şe *button* (*Press Coat Buttons*) ki awọn af'aşọ-dara (*Expert Tailors*) maşe jafara lati ba ra tiwọn; ọpọku-ọyọku ni ọja meremere wọnyi.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

A-TANRẸRẸ BI EJINRIN,
Ẹ KO RI'ŞẸ OLUWA?

O dun mọ ni gidigidi lati gbọ pe awọn Ijọ *Bethel* ni ilẹyi fi enia meji j'oye Alufa ni Ile-isin wọn ni *Sunday* to kọja fun Şọşi wọn ni *Calabar*; laisi aniani Ijọ *Bethel* ndi araba t'apa ọmọde ko ka. Eyi wu wa o.

ALABUKUNFUN NI AWỌN ONILAJA.

Irohin kan ni lati Iga Idunganran wa ninu ọsẹ yi pe Olowo pẹlu awọn Agbagba miran pari gbolohun-aşọ to wa larin Ọbanikoro ati Ọjọra ni Satide to kọja; ati pe lẹhin ipari-ija na tan Ọjọra ba Ọbanikoro lọ sile; a si tun gbọ pe ni *Sunday* to kọja, awọn Oloye mejeji yi ranşẹ ki ara wọn.

Olowo sọ pe Oniru ranşẹ pe ara on ko da, şugbọn o fi ikọ mẹrin şọwọ, o si sọ pe on wa pẹlu gbogbo atunşe ti Olowo ba şe ni Iga.

A ŞORO PE NI'TA EREKO!
INA O O O O!!!

Ni dede agogo mẹta oru *Tuesday* ọsẹ yi ina kan şẹ ni agbo-ile Ọgbẹni James George ni Ita Bamgboşe leti Şabu Ọgbẹni J. A. Thomas; a si pa ki o to r'aye şe jamba pupọ siwaju. A ki Ọgbẹni Eman: James George ati awọn ara ile na. Ẹ ku ewu.

INA LO WA GBA NI TABI BEER
LO WA KO?

Igbati-igbamu ni awọn kan fi bere ọrọ oke yi lọwọ ogbole kan ni fẹrẹkilẹmọ *Thursday* ọsẹ yi nigbati ina fi şẹ nile Iya Afin Sẹlia ti o ni Şabu Beer ni 9, Ọbadina Street. Bi gbogbo enia ti ndaro ti nwọn si ngba ina, bẹni alafọwọra yi nọ igo *Beck's Beer* mọra giri, ti o si mẹhọ.

Gba gbo ti nwọn şana loju rẹ, mu ki a mu lọ sile Tinubu Iyalode, Aniwura.

KALAMU TUN JA SI KOTO!
KI LA RI YI WẸ?

O dun ni pupọ lati tun gbọ pe Adele Adajọ Agba A. F. C. Webber rọ pipete şişe Ap'li fun ọrọ Prince Eşugbayi ni 'di ni Alamisi ọsẹ yi, niwaju awọn Lọya ti a gba fun ẹjọ na.

Ẹjọ nipa ti pe ki Prince Eşugbayi papa ba le wa si Ganran lati wa sọ ti ẹnu rẹ (Irufẹ ẹjọ bẹ ni a npe ni Hebiasi Kọpọsi) şi sun; titi yio fi fuyẹ fun Ọgbẹni A. D. A. MacGregor, Adele Agbẹjọro Ọba lati fọnsi pẹlu awọn Lọya apakeji.

ẸNIKEJI,

Aşọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, *St. John Street*, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

## "EKO AKETE" LAW REPORT.

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

Niwaju Adele Adajọ Agba A. F. C. Webber ni ijọ *Friday* ijọ kejidilogun oṣu *September, 1925*.

STATED CASE.

REX *versus* JOSHUA ABIODUN LEIGH

Lọya Shyngle lo wa fun Alufa Joshua Abiọdun Leigh ati Lọya Jonathan Collins Zizer.

Lọya Shyngle dide o ni ohun ti on ba wa siwaju Kotu ni pe ko si ọrọ nipa wipe ẹlomiran ri iwe na, o ni bi o ba ri iwe gba, o ni lati mu ẹniti o mu irufẹ iwe na wa si Kotu.

(The only ground is want of publication. The evidence to publication will be found in Pege 2 of the deposition. I submit that when you receive letter by post you must produce the postman.)

I am referring to Archbold p 1249. Lọya Shyngle tun sọrọ pupọ nipa wipe bi ohun ti on sọ ko ba tẹ Adajọ lọrun, ko jọwọ ko mu ti ẹwọn oṣu meji yẹn kuro ko jẹ ko san owo (I am referring your Honour to Vol. 1 of the ordinance page 179 of the Criminal Code.

Agbẹjọro Ọba Ọgbẹni Blackhall dide. O ni awọn ẹlẹri fi han gadagba pe Alufa Leigh lo kọ iwe na (It was proved that the handwriting is accused's writing through the Banking experts.) The Court has no power to alter the sentence.

Lọya Shyngle dide o fi ọrọ we ọrọ nipa gẹgẹ bi Adajọ ti ni aṣẹ lati yọ ti ẹwọn kuro.

Court :—I see no ground to reduce the sentence.

Appeal dismissed

Niwaju Adajo Agba ni ijọ *Monday* ijọ kokanlelogun oṣu *September, 1925*.

STATED CASE.

REX *versus* E. A. KING and others.

Ẹjọ yi ni awon enia bi marun kan ti awọn Ọlọpa ki mọlẹ ni *Hotel* David David ni Ebute Mẹta fun ẹsun wipe nwọn nta tẹtẹ ni alẹ ọjọ na. Ti wọn si lu Lambert Davies *Inspector of Police* nitori ki nwọn ba ri aiye salọ. Nigbati ẹjọ yi de Kotu Adajọ Ebute Mẹta ni ki wọn san pọwun kọkan tabi ẹwọn ijọ meje. Eyi ko te wọn lọrun wọn gbe ẹjọ wọn wa si Ganran ni Eko.

Lọya Thomas lo ṣe ẹjọ yi.

Lọya Thomas for the Appellants.

He refers the Court to Archbold 26 Edition page 1302.

REGINA *versus* DAVIES

Court :—Case dismissed.

REX *versus* TOKOSI

W. Williams for the Appellant.

Martins for the Respondent.

After an able argument by the Counsel for Appellant. The Judge found no ground consider the point of law submitted by the co[unsel] for the Appellant. Therefore the case was [dis]missed with £5 5 0. Costs to the respondent.

In the matter of an order under the hand of Officer Administering the Government dated day of August 1925, and also an order under said Officer and seal of the Colony and Pro[tec]torate of Nigeria dated the 8th day of Au[gust] 1925, under the deposed Chiefs Remo[val] Ordinance Chap 78 Sect. 2 concerning Eshugbayi Eleko.

Motion by Joseph Egerton Shyngle.

Shyngle :—I appear to move with my learned friends Messrs. Ayọ Williams, W. Williams J. C. Zizer.

Shyngle :—I am asking for leave to serve issue, and further leave to serve Mr. R. H. Lapage District Officer, Oyo. I am asking for leave serve the District Officer, Oyo because it is outs[ide] the jurisdiction and also leave to serve the Offi[cer] Administering the Government. See page 45 the Supreme Court Ordinance Vol. 3.

I withdraw the application for leave to ser[ve] Lapage but to serve the Offcer, Administering Government because he is the only one that c[an] give Order for his release.

Court :—Leave granted to serve the Offi[cer] Administering the Government.
Motion adjourned till Thursday the 24th inst.

ESHUGBAYI ELEKO

*versus*

FRANK MORRISH BADDELEY and T. S. W. THOM[SON]

Suit No. 299/25

Motion for leave to appeal on the judgment this Honourable Court delivered on the 7th d[ay] of September 1925, on a motion filed by the Attorney General on behalf of the 2 defendants to dismiss or stay an action mentioned above on the grounds that it is frivolous, vexatious and abuse to the process of this Honourable Court.

Shyngle moved on behalf of the plaintiff.

Court. I'll give my decision on Thursday the 24th instant.

Niwaju Adajọ Kotu Ọlọpa Ọgbẹni M. C. Greene ni ijo *Thursday* ogunjọ oṣu *August 1925.*

Ọlọpa mu Isobo kan ti orukọ rẹ njẹ Peter fun ẹsun wipe o ji pọwun mẹdọgbọn *( Stealing the sum of £25 Cash property of one* Agboro *at Wesley Street, Lagos, )* owo Ọgbẹni ti oruko, rẹ njẹ Agboro to ngbe ita *Wesley* ni Eko. Ọgbẹni Agboro yi wa ta Epo ni Eko nibi, o si wọ sile aburo rẹ nibiti aburo kanna yi gbe gba igara to pe ni ọrẹ rẹ yi si, nigbati Agboro gba' diẹ ninu owo Epo na pọnun mẹdọgbọn o ni ki igara ole yi ba on fi pamọ nitoripe aburo on ti on wọ sile rẹ yi on ko ba nibi nitori o ba Oyinbo rẹ lọ si ẹhin odi, igara ole yi ni ṣe awa mẹta lo kuku ngbe ile, emi, iwọ ati aburo nyin kekere ta lo wa gbe pọnun mẹdọgbọn ti awa mẹtẹta fi oju ri lọ, gbogbo wọn sun, orun ko kun Peteru ole, ka ma da ena pẹnu, kilẹ to mọ Peter ti gbọn gbu o ti fi ẹsẹ fẹ pẹlu pọnun mẹdọgbọn nigbati ilẹ mọ, oju Agboro ṣokun nitori ko ri owo rẹ mọ, o wa Peter ko ri Peter. Ẹnyin enia wa, ki lẹ ṣebi Peter ṣe o lọ si Ṣabu Fairley o ge aṣọ *Black Black*, o lọ ṣi Ṣabu Lomas o ra Bata *Lotus* to jire, o ra *Monocle* to pe o si dawo si Jẹkiri *Dance Ball* ti wọn jo ni *Empire Hall* ni ọsẹ na, o ti haya ile omiran,, *London opinion* rẹ ndan yẹri, eyi ta wi yi ti pẹju Peter nṣe bi alara. Agboro ti lọ si Ṣabu awọn Ọtẹlẹ muyẹ awọn ẹlẹgiri ti gbalẹ yika, warawere wọn ti ga Peteru ole yi. Peter ni *Port Harcourt* ni on ti wa, on si mu owo bọ on ko si mo ẹniti o njẹ Agboro yi ri, akọkọ ti on ma ri ni yi. Aṣa-mọ-ṣamọ ẹwọn ti wọn ju Peter si *Port Harcout* lo iọ lo ẹwọn na, ijọ kẹrin ti Peter de Eko ni o wa pa Agboro lara. Adajọ ni Peter jẹbi. O ni ki Agboro ko gbogbo dukia ti Peter ṣẹṣẹ ra titun. Lẹhinna ni awọn Ọlọpa mu iwe Peteru wa wipe o ni bara awọn ni, o di igba kẹrin to ti wọ ẹwọn. Peter ni awọn Ọlọpa korira on ni on ko wo ẹwọn ri, warawere wọn mu Photo rẹ jade, o di oju ole re, ole, Adajọ ni ki Peter lọ si ẹwọn oṣu mẹfa pẹlu iṣẹ Asegan.

## SUPREME COURT NOTICE

---

ASSIZES EASTERN DIVISION

The following Provisional dates are fixed for holding Niger Assizes.

Warri 9th November 1925
Lọkọja 18th November 1925
Onitsha 23rd November 1925
Enugu 30th November 1925

Dated at Lagos this 19th of September 1925.

By order,
(Sgd) T. B. BUKO,
*Acting Chief Registrar.*

Ẹnyin Lọya wa ẹjọ Ganran ti Odo Ọya ṣi ni oṣu *November* ọdun yi, ẹ gbara di. Eyi yi ni ifi lọ ẹkeji.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATOLUGBOKUN.

---

**Address presented by the African Bethel Church, Parish Committee, on behalf of African Bethel Church Congregation, Lagos, to Rev. A Aboyade-Cole to commemorate the occasion of his Ordination to Deacon's Order which took place at the African Salem Church, Ebute Metta, on Sunday the 7th day of June, 1925.**

---

Rev. Bro. A. Aboyade-Cole,
Palm Church Street,
Lagos.

Rev. Sir and Dear Brother in Christ,

We the undersigned, on behalf of this Committee and the Congregation of African Bethel Church, Lagos, avail ourselves of this golden opportunity to congratulate you on the occasion of your Ordination as a Deacon in the African Church Organization, and to express our hearty good wishes for your future progress in this circle.

We feel it necessary to place on record the most valuable services rendered by you to the Parish of Bethel Church after the death of the late Minister-in-Charge *(* Rev. E. A, Akinola *).*

We are also proud of the great talent which God has given you and by which you have been able to build up many Societies in and outside this Organization, and we sincerely pray that God may grant you more health to be able to conscientiously and satisfactorily perform your duties on the new sea on which you have just placed your barque.

In view of the above facts, we ask you kindly to accept this present not on its intrinsic value but on the good motive that has prompted it.

We wish you, Mrs. Cole and other members of the family once more health and prosperity.

We are,
Rev. and Dear Brother,
Yours in Christ,

*(Sgd)* J. SOTAYO WILLIAMS—*Chairman,*
" PHILLIP T. CORRR—*Warden,*
" J. OKAN. THOMAS—*Secretary.*

---

## A Lady Medical Officer to the Fore.

Miss H. S. Kerr, M.B., CH.B., D.T.M. and H., Lady Medical Officer appointed for Nigeria.

*See West Africa 22/8/25.*

## ONIRURU OWO TI A SAN SI APO IGBIMỌ MUNISIPA EKO. NI ỌDUN 1924—1925.

| | | £ | s. | d. |
|---|---|---|---|---|
| 1. | Owo ti awọn Onigbanjo san | 555 | 4 | 0 |
| 2. | Owo Aja | 90 | 14 | 0 |
| 3. | Owo Iwe lati le ta Ọti | 3,164 | 0 | 0 |
| 4. | Owo Iwe lati le ma patẹ Ọja | 54 | 0 | 0 |
| 5. | Owo Pẹtrol | 40 | 0 | 0 |
| 6. | Owo lori Ẹran ọsin mimu ni adugbo | 136 | 18 | 8 |
| 7. | Owo ti awọn Alapata Ẹran san | 1,810 | 5 | 0 |
| 8. | Owo Ẹran pipa ninu ile | 28 | 0 | 6 |
| 9. | Owo Iwe Isinku ati owo sare ( *Vault* ) | 635 | 2 | 5 |
| 10. | Owo ti a nsan lori panu igbọnsẹ ( Po ) Ọba ti a nlo ( *Sanitary Pails* ) | 90 | 9 | 0 |
| 11. | Owo ti a ngba lori Kẹkẹ orişirişi ati Bicycle | 2,927 | 16 | 6 |
| 12. | Owo ti a ngba lori Motọ Kẹkẹ Ẹru | 5,431 | 14 | 3 |
| 13. | Owo ti awọn Awamoto nsan | 457 | 13 | 0 |
| 14. | Owo ti awọn ti o jẹbi yanmuyanmu ati ẹşẹ miran ni Kotu san | 1,752 | 13 | 6 |
| 15. | Owo Iyoda lati le kọle | 70 | 7 | 6 |
| 16. | Owo *Plan* Ile | 228 | 4 | 6 |
| 17. | Owo Ọkọ &c | 181 | 6 | 0 |
| 18. | Owo *Fine* lẹnu Işẹ Ọba | 9 | 11 | 2 |
| 19. | Owo *Theatre* ( Ere şişe ni ile ere ) | 30 | 10 | 0 |
| 20. | Owo Omi ( *Water Rates* ) | 11,930 | 6 | 7 |
| 21. | Owo ti awọn ti nşe Burẹdi nsan | 17 | 5 | 0 |
| 22. | Owo wẹwẹwẹ miran ti a nsan | 814 | 6 | 8 |
| 23. | Owo Iwe fun Kẹkẹ Motọ titun | 147 | 8 | 0 |
| 24. | Owo ti awọn ti nya enia lowo ele pẹlu fifi ohun elo bi *Gold* dogo san | Ko si | | |
| 25. | Owo ti a fi tun ilu şe | 2,525 | 18 | 10 |
| 26. | Owo ti a fi tun oniruru ile Ijọba şe | 2,000 | 0 | 0 |
| 27. | Owo ti Ijọba papa yọda fun nina sori ilu | 1,000 | 0 | 0 |
| 28. | Owo orişirişi miran ti a ri gba | 294 | 16 | 2 |
| 29. | Owo Iwe fun ati le şe *Cinema* | 62 | 10 | 0 |
| 30. | Owo Ilu ( *Drumming Fees* ) | 213 | 10 | 0 |
| | Aropọ | £37,170 | 11 | 3 |

*( Sgd )* IVOR C. WATTON,
*Adele Akọwe Munisipal.*

Lati inu we Irohin Ijọba ( *Nigeria Gazette* ) ti *September 17, 1925.*


## The " B'yotiri " Mart.

B. O. JOSEPH,

*Licensed Auctioneer, Commission and Estate Agent, Valuer and Appraiser.*

22, Church Street, Lagos, Nigeria.
(Near Carter Bridge).

Undertakes the sale of all kinds of goods also landed properties either by private contract or public auction in any part of Nigeria.

He is also willing to act as commission agent to any of the local firms.

*(Over 21 years' experience in trade.)*

**Cotton, Sundries, Hardware Provisions.**

Prompt rendering of accounts and quick payments. Moderate Charges.

Sales on MONDAYS and THURSDAYS. Commencing at 9 a.m.

*Emergency Excepted.*

Patronage is respectfully solicited.

*Telegrams*
"BEN. JOSEPH" Lagos

The Mart and Office,
22, Church Street,
Lagos, Nigeria.

*Residence,*
35, Richards Lane,
Lagos, Nigeria.

## TO LET OR LEASE.

A very commodious shop suitable for commercial purposes, situate and being at No. 21, Bishop Street, Lagos, presently occupied by Messrs. G. B. Ollivant & Co., Ltd. and will be vacated on the 8th of October, 1925.

ALSO

A Land at No. 39, Patey Street, Ebute Metta, measuring 25 x 105 feet, suitable for residential purposes.

For particulars apply to:—

B. O. JOSEPH,
*Licensed Auctioneer, etc.*

The B'yotiri Mart,
22, Church Street,
( Near Carter Bridge )
Ebute Ero,
or 35, Richards Lane,
Lagos.

Mrs. Beckley of No. 53 Broad Street begs to announce that she has started cake-baking of all kinds; ever ready to serve !

GUARANTEED

THE RALEIGH

FOR EVER



# RALEIGH

## THE ALL-STEEL BICYCLE

## MILLER BROS. (L'pool) LTD.,

## LAGOS.

# EKO AKETE

EKO, SATURDAY, SEPTEMBER 26, 1925.

## ȘUGBỌN GBOGBO ỌRỌ YI L'A RÒ FUN ILU, ILU SI DAKẸ !!!

Jamba igbagbogbo ti mọto nta fun t'ọmọde t'agba nilẹ yi, lemọlemọ nisisiyi mu wa sọ gbolohun ọrọ meji-mẹta si ni ọsẹ diẹ sẹhin, ni ireti pe boya awọn Ijọba tabi awọn Alagbara miran ni'lu yio ri si ohun ti a sọ na, ati pe nwọn yio si wa ọna didin irufẹ agbako bẹ ku; șugbọn lati igbati a ti sọ eyi a ko gbọ pá, bẹni a ko si gbọ mu; bayi ni Ilu si dakẹ.

A fẹ bere pe ṣe iti mọto yio fi ma ṣe awọn enia leṣe ni igboro Eko nigbagbogbo bayi, bẹni a ko ni ri ẹni dasi? Ọrọ iku gbigbona ti mọto wọnyi nṣe ikọ wọn ma ṣẹ nkuro ni ki a ma fi ọwọ-lẹran ki a si joye a-wò-sũ-șekan; nijọ wo ni eyi na, ti awa-mọto kan pẹlu ọmọ-iṣẹ rẹ fi ti ori kereni *Carter* re sọ s'omi nigbati nwọn nlọ si ọna Iddo? Ni ọjọ diẹ s'ẹhin si tunkọ ni Ọgbẹni Moloney Johnson ti Alli Street, kan agbako tirẹ nipa *petrol* ti o jo tobẹ ti o fi lọ s'alẹde ọrun bi ọmọde meji nṣere? Ni arọ *Monday* ọsẹ yi ẹwẹ, kọ ni a tun gbọ pe mọto pa ọmọde-Linrin kekere kan ẹniti iya rẹ nlọ ra akara fun, ni apadọrun ni Lafiaji l'apa adugbo Alhaji Lawani Martins ni Hawley Street, a sọ fun ni pe wẹn-ẹn bi mọto na ti rin ọmọde yi mọlẹ, nigbati awọn enia rọ gìàìgìdì de ibẹ nwọn ko ba ẹmi kan l'ẹnu rẹ mọ; *La Ilaha Illa 'Lau, Muhammad Rasul Lah*, BABA MIMỌ GBA NI!!! Bẹ tun ni, ni alẹ *Sunday* to kọja ti a ri awọn kan pe ṣũru-ṣũru l'eti Ile Dokita Macaulay ni *Victoria Street*, ati mọto bi meji mẹta laisi ani-ani, agbako mọto lo sun awọn enia wọnyi de'bẹ; ṣe eyi ti a nri tabi ti a ngbọ ni a sọ yi, ọgọrọ jamba miran ko ha mbẹ l'ọna oko ati l'ọna odo; melo ni a o ka ninu ehin (*teeth*) Adepele? Kàkà ki o san lara Ajẹ, o nfi gbogbo ọmọ rẹ b'obinrin ẹiyẹ njogun ẹiyẹ; kàkà ki ewu ati iku mọto dinku, npele lo npele si i.

Nitorina a tun ke si ẹnyin Ilu, ki ẹ maṣe dakẹ si bi awọn enia ti nku gifa bayi: ko si ẹniti ki ngbadura pe ki on f'owọ rọ'ri ku, nigbati akoko ba to fun ẹlẹru lati gbe e; ṣugbọn nigbati o ba ṣe ndi pe ki a ṣa egungun ẹni l'eni tere, eji tere, da sinu posi, tabi ki a gbe ọwọ ẹni tabi ẹsẹ ẹni bi igbati awọn ọmọde iba ma kọrin pe "A gbe baba, o-jo-nto, a gbe baba, o-jo-nto" ki a si lọ sin awọn ọwọ ati awọn ẹsẹ wọnyi lọ̀tọ̀lọ̀tọ̀ nigbati ọlọwọ tabi ẹlẹsẹ pãpã ko ti ku, ko di ọwọ miran ndan?

Bi a wipe ki a bi awọn Ọga-ọlọpa ire agbako mọto ti nwọn nṣalabapade l'oṣoṣu l'ẹnu oṣu mẹta yi wa, Hă, yio ṣe ọnikẹni. Ẹnyin Ijọba, ẹnyin Olori Ilu, ẹnyin ti ẹnu nyin to'lẹ gbogbo, ẹ jare, ẹ ma ma dakẹ si ọrọ iku ati jamba moto igbagbogbo yi. Ẹ ṣanu enia, ẹ ṣanu Ọmọ-orukan, ẹ ṣanu MARIA ỌLỌRUN gbogbo.

Ẹ gbaradi; ẹ ṣanu awọn Abiamọ gbogbo.

Kò to nkan, kò to nkan, ma ni fila Imale fi nku pẹ́ẹ́í, A bẹ̀rẹ̀ o !!!

## EWO L'A NṢE O!

[ *Lati ọwọ* KEKERE ILU.]

Si Oniwe-Irohin *Eko Akete.*

Lẹhin ti a ti kọ wosika wa ọsẹ to kọja ni a gbọ ọrọ meji mẹta ti a o sọ gbolohun kokan le lori ki a to mu ẹnu le ọrọ ti ọsẹ yi papa. Ṣiwaju, a ni pe o yẹ ki a pa ileri wa lori itan ọrọ Ọba Eleko ti, nitori bi a ba ma sọ ọ, o le gba wa ni ọsẹ meji mẹta, bẹni a nfẹ ki Ilu wa iṣẹ atata ṣe. Eni, ọrọ Eleko; ọla ọro Eleko; yio dabi ẹni ndi Ilu-lọwọ dipo ti yio ran a lọwọ. Atilẹhin fun ilọsiwaju-si l'olori. Iba o!

Niti ọrọ ti a gbọ, ẹjọ Oloye Ọbanikoro ọlọ... O jẹ ohun iyanu pe iru Oloye alagba bi rẹ, ẹniti ni on wa ni ipo aṣiwaju gbogbo Oloye Eko, le... ofin l'oju l'ọna bẹ. Iru ohun ti o ṣẹ ni Ilu ni ọsẹ to kọja ati ira ti Oloye yi ko ninu rẹ to lati fihan... pe bi Ilu tilẹ ti fẹran rẹ ri, inu wọn ko le dun si... Ṣugbọn o mọ ipo wo ni on ti wa pẹlu Ilu lati... ọdun mẹjọ tabi ju bẹ lọ sẹhin. Bawo ni o ti ṣe...

pe yio ma jo pẹlu orin apara si Ọba Eleko ti Ilu nṣọfọ rẹ ki awọn to wa ni iha ti Ọba na ma wa ṣifila tabi wari fun on? Ti ko ba si pe a nfẹ efẹ a le rojo "ṣifila"? Papa, ki a mu enia lati ilun kan lọ si ile ẹni lọ na kuro ni nkan ṣere-ṣere. Ija pipe gan ni, nitori bi awọn agbọrandun, tabi ẹbi, tabi ọrẹ, ẹni ti a jẹ ni iya lọna iwọsi bẹ ko ba ranti ofin ki nwọn lọ gbagbera binu, kini iba ti ri? O ha tọ ki a gbọ pe ni akoko ti oju la bavi Oloye alagba bẹ lo da ijagboro silẹ ni ilu? Ẹni a na l'ara nta l'a gbọ. Oloye pẹlu awọn ẹni rẹ iba jẹ ẹni Ijọba lọna rere nipa wiwa alafia ilu bi o ba jẹ pe eyi ti nwọn fi njo ajobu kakiri Isalẹ Eko, nwon nfa awọn ti nwọn ti gbelulẹ l'ọtun l'osi, pe "Ẹ gberaso, ija ti sun, o di ṣiṣe rebẹ, k'ọkọ ki rin!" Ina-ku-na ko si ninu aṣẹ ti a fun Gomina papa, ki a ma ṣẹṣẹ pe Oloye, tabi ẹnikan gunmọ! Ohun to yẹ ni l'o yẹ'ni, okun ọrun ko y'adiẹ. Toto o!

Ọrọ keji ni ti ẹjọ ti a tun gbọ pe o nlọsiwaju. Bi awọn Loya fi oye rẹ ye Ilu, bi awọn ko ṣe e, a ko mọ. Bi a ti ri oro si ni a sọ l'ẹsẹ to kọja yẹn. Ṣugbọn, ohungbogbo ko ṣẹhin Ọlọrun. Boya ki a to jade awọn Loya ti Eleko ati ti Ijọba yio ti wọya ija, boya ikan a si ti da ikeji. Owo a funa!

Ewo l'a nṣe o! Nwọn ni to ba ngbọ gbe-gbe-gbe bi o ba tete, gbi! li ō gbo lẹhinkule rẹ. A nfi ogun ara wa ṣe alokunna. Idi oraye ati iregbe ti ko ni ori ni a joko kẹtẹnfẹ si, be a gbọ pe Gomina titun mbọ, a si gbọ pe Igbakeji-Sẹkitẹri-Agba ti Ilu Oyinbo nfẹ wa bẹ ilu wa wo.

Ni lọwọlọwọ yi ni ọrọ ilẹ wa tun gbode. Bi a ba ni tanma pe iyẹn ti wa-alọ, ko si kuku, a o sọ omi-laipẹ. Bi a ba mọ Gẹsi bi ẹni mọ owo, a o mọ pe ti ilu kan ba wa lalai ni olaju ni amọna suru wọn de gongo, ẹru Ọlọrun si ma nba wọn. Ṣugbọn ibi ti enia to riran ba wa ti nwọn nṣe ira, orin yi ni nwọn ma kọ fun wọn: "Gigọ t'ọgọ, ọ ba l'ola!" Iru rẹ ni ti ọrọ Ọba wa ti nwọn wa wa dẹ, wa wa dẹ, ti a fi aye silẹ fun wọn lati ra si wa l'abẹ.

Ọrọ ilẹ ọrọ kekere ko fun awọn Oyinbo. Ilu wọn fun, ọmọ-eni. Iṣura ti Ọlọrun fi fun ilẹ wa wulo fun wọn, nwọn o si le fi wọn ṣere. Ninu Iwe-irohin (*Report*) ti Igbakeji-Sẹkitẹri-Agba ṣe pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ fun Ilebimọ A'ofin Ilu Gẹsi lori lilọ ti nwọn ran wọn lọ si Iha ila-orun Ilu Enia Dudu (*East Africa*) nwọn sọ ṣako pe ọrọ Enia Dudu ki nṣe ọrọ kekere. Awọn ni lati jẹ olutọju fun wọn nitotọ ṣugbọn gẹgẹ bi ọrọ Lugard, awọn ni lati ro ti gbogbo aiye pẹlu. Iyẹn ni pe, bi ilẹ ba wa lasan ti a o ro o, ti a o wa a, yio jẹ adanu fun awọn Ilu mi ti nwọn mọ riri iṣura, eso tabi nkan-elo ti Ọlọrun fi ṣe ikẹ Enia Dudu, awọn ko si ni lati fi aye silẹ fun atara irufẹ bẹ. Bi awọn ara-ilu ko ba ṣ ṣẹ awọn ni lati mu wọn ṣiṣẹ fun ara wọn, fun ilọsiwaju ilu ati fun anfani awọn ilu yoku. Lọrọ kan awọn Oyinbo nfẹ ekurọ, nwọn nfẹ epo, ẹyin, nwọn nfẹ adi, nwọn nfẹ owu, nwọn nfẹ wura, nwọn nfẹ *rubber*, nwọn nfẹ gẹdu, nwọn nfẹ yẹpẹ-panu, edu, epo-inu-ilẹ, diamondi, ati ohun iṣura ati nkan owo ti o ya haramu ni ilẹ Enia Dudu ṣugbọn ti a o mọ iyi pupọ ninu wọn. Irọ ha ni bi? Tani njẹ anfani awọn nkan ilẹ wa ju? Awa ni tabi Oyinbo? Ti o ba wa di pe awọn papa wa ndako ni ilu wa, njẹ fifun ko ni wọ o? Bẹni ikan l'ao ṣe. Yala ki a ji l'asiko, nipataki awa ti iha ibi yi ti Oyinbo ko yi ti wa fidikalẹ ti—nwọn ṣa nlọ nwọn mbọ ni—ki a kọ ọgbọn ati ẹrọ ti a le fi ma yọ gbogbo ohun ti Oyinbo nfẹ jade fun wọn ninu ilẹ wa, ọranyan ni pe ọgbọgbọn awọn papa yio ma sun de idi rẹ.

Eyi ti Ọlọla Lord Leverhulme sọ ki o to ku si nja ranyin nilẹ nisisiyi, bẹni a o ti taji. Ewo l'a nṣe o? Awọn Oyinbo ṣa nja fun wa to, awa na ko ni bẹrẹ fọwọ gbe ẹru wa? Nwọn nkọ awọn ọmọ wa ni iṣẹ agbẹ ni Ibadan. Bi a ba ṣatilẹhin fun awọn ọmọde diẹ ki nwọn roju kọ iṣẹ yi, ti a si fa Ijọba ni papankoko pe ki nwọn ran diẹ ninu wọn lọ si Ilu Oyinbo ati Amẹrika lati ba ni mimọ si l'oniru-iru ọna iṣẹ agbẹ ninu owo-ilu ti Ijọba ngba yio yẹ wa yẹ wa! Ọrọ ilu wa ngbero. O nfẹ ero. Ẹ jẹ ki a fi ero si i ki anfani gbogbo ma bọ lọwọ wa o!

KEKERE ILU.

---

## *THE EDITOR'S OBSERVATORY.*

### A Good Cinema Treat.

We learn that on Wednesday the 16th instant, a selected number of Africans that is, Mr. and Mrs. Henry Carr, Hon. and Mrs Kitoyi Ajasa, and Mrs. Oyinkan Abayomi, Mr. and Mrs. Adeyemo Alakija and some members of the Executive Council, on the invitation of The Honourable the Acting Chief Secretary to the Government, Mr. T. S. W. Thomas, witnessed a Private Cinema View which was held at the residence of the Acting Chief Secretary in respect of some scenes in connection with last visit of His Royal Highness the Prince of Wales: the pictures, it is said, were A.1. at Lloyd's.

### Another Leg before the Wicket? What a pity!

At about 9 a.m. on Thursday last, His Honour A. F. C. Webber, Acting Chief Justice in the Supreme Court, opposed in a learned "Judgment" the Motion for Leave to appeal which was filed by counsel for the plaintiff, *in re* Esugbayi *versus* F. M. Baddeley and T. S. W. Thomas.

Owing to the indisposition of the Hon. the Acting Attorney-General, Mr. A. D. A. MacGregor, the argument of counsel relative to the *Habeas Corpus* business, was deferred.

### Would our Road-Hogs like this?

Elsewhere is published an extract from a foreign newspaper with regard to how reckless Motor drivers in Idianapolis (New York) "who ran down and kill pedestrians" would be treated in that country when charged with manslaughter the result of their mad and insensate driving to the danger of life and limb in the public

*A Grim Punishment.*

New York,—The Indianapolis city authorities have decreed that reckless motorists who ran down and kill pedestrians must spend an hour in the mortuary alone with the body of the victim. It is hoped that this punishment will duly impress drivers with the tragic fruits of their carelessness, and so lead to a diminution of street accidents.

We wonder, how many of our Motor-drivers would like a "job" like this.

---

## ẸHIN RE O, ẸHIN, Ẹ WA WO'KU ỌLỌMỌ!

Ni dede agogo mejila kọja ni arọ Satide, *19th September, 1925*, ni a gbọ iku Iya Ọgbẹni wa N. T. O. Davies ti o ṣẹlẹ ni 22, Taiwo Street, a si gbe Iya na lọ si Ile Isin Onidunkun, (*St. Paul's Breadfruit Church*) ni iwọn agogo mẹrin irọlẹ, Aṣidikini Ogunbiyi sọ ọrọ ọmọluwabi lori oku Iya ati wipe o ri awọn ọmọ rẹ kẹrin.

Iya wa na jẹ oninure. Ki Oluwa Ọbangiji ki o gbe si afẹfẹ rere.

A ki Ọgbẹni N. T. O. Davies, Iyawo rẹ ati Adebisi, Beatrice, Victoria, ati Elizabeth Aina Davies, ati gbogbo awọn ẹbi ẹ ku aṣẹhinde, ẹ ku inawo o. Ẹhin Iya a dara.

---

## "EKO AKETE"

EVENING CLASSES

for those who desire to improve their knowledge of the English Language.

SUBJECTS :—

Paraphrasing : Essay-writing, Correction of Faulty Sentences, The Use of Foreign Words and Phrases, The Use of Idioms.

Pronunciation of some queer names of persons, titles and Places.

Composition : Translation into Yoruba, Translation into English, Letter-writing, Spelling :

Classes begin at the "Eko Akete" Offices on Wednesday the 30th September, 1925, at 7.30 p.m.

Fee : 2/6d monthly for all subjects. Payable in advance.

For further particulars :—

Please apply at "Eko Akete" Offices, 22 & 24, Williams St., Lagos.

P. O. Box 286.

**Enia Soro Medicine and General Stores.**

SHAPON—ITOKU ROAD, ABEOKUTA.

Ẹ o ri ogun Ikọ, Atura ọkunrin; ogun Ọrin, Igbẹ ṣoro, Inukikun, ti obinrin ko ba ri nkan osu rẹ; Aitete loyun, Ewo, Apeta Igbẹ ẹjẹ, Atọsi, Ẹda, ati oriṣiriṣi arun nba obinrin ati ọkunrin ja, lọ si ibẹ. Ow pọ̃ ni wọn jasi.

The West African Soap Co. Limited
APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

NEPTUNE
PALE SOAP

BUGLE
PALE SOAP

MAGNET
CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

P 302

## IROHIN ABẸOKUTA.

